# IRUGBIN MUSTARDI ATI IWUKARA
## Matteu 13:31-33
## ẸKỌ 77 FUN AWỌN ỌDỌ

**AKỌSORI: "Nigbana li awọn olododo yio ma ràn bi õrun ni ijọba Baba wọn" (Matteu 13:43).**

### A Kọ Awọn Ju nitori Aigbagbọ́

A kọ́ ninu ẹkọ wa ikẹyin pe Ijọba Ọrun bẹrẹ nigba ti Jesu wà ninu ayé. Jesu rin kaakiri O n waasu nipa Ijọba Rẹ̀ nibi gbogbo fun Ju ṣaaju ati fun Heleni pẹlu.

Awọn Ju jẹ́ ayanfẹ Ọlọrun, awọn ni a si kà si ọmọ Ilẹ-ọba tẹlẹri; ṣugbọn nigba ti wọn kọ̀ lati naani ẹkọ Jesu, O wi pe: "Mo si wi fun nyin, ọ̀pọlọpọ enia ni yio ti ìha ìla-õrùn ati ìha ìwọ-õrùn wá, nwọn a si ba Abrahamu, ati Isaaki, ati Jakọbu joko ni ilẹ-ọba ọrun. Ṣugbọn awọn ọmọ ilẹ-ọba li a o sọ sinu okunkun lode, nibẹ̀ li ẹkún on ipahinkeke yio gbe wà" (Matteu 8:11, 12). Awọn wọnni ti yoo "ti iha ila-õrun ati iha iwọ-õrun wá" ni awọn Onigbagbọ́ laaarin awọn Keferi. Ọlọrun ti fun gbogbo wa ni anfaani lati wọ inu Ijọba Rẹ̀.

### "Awọn Ohun Wère Aiye"

Jesu fi Ijọba Rẹ̀ wé irugbin mustardi. Ni ilu nì, irugbin mustardi jẹ ọkan ninu awọn irugbin ti o kere ju lọ, ṣugbọn igi rẹ a maa dagba ju ewebẹ-kewebẹ lọ -- o fẹrẹ ga to igi nla. Ni akoko ti Jesu n waasu, Ijọba Rẹ̀ kere lọpọlọpọ. O waasu fun kiki awọn Ju, a si mọ̀ pe ni Ọjọ Pẹntekọsti iba ọgọfa eniyan (120) ni o gbọran si aṣẹ Rẹ̀ lati duro ni iyara oke titi a fi fi agbara wọ̀ wọn lati oke wa. Awọn eniyan ti wọn ti jẹ ipe Rẹ̀ ki i ṣe ẹni nla gẹgẹ bi awọn araye ti n pe eniyan ni nla; wọn jẹ lara awọn apẹja, agbowode, òtọṣi, awọn ti a ko ka si. Ṣugbọn Jesu ti "yàn awọn ohun wère aiye lati fi dãmu awọn ọlọgbọ́n" (1 Kọrinti 1:27).

Lẹyin ti Ẹmi Mimọ́ bà le awọn ọmọ-ẹyin, wọn gba agbara lati lọ si gbogbo aye lati waasu ọrọ Ijọba naa. O ti bẹrẹ si dagba. Awọn eniyan alailera ti wọn ti sá lọ kuro ninu ọgbà nigba ti awọn ero wá lati mu Jesu, wọn ti ni agbara nisisiyii lati duro pẹlu igboya fun ẹkọ naa ati lati waasu Ihinrere Ijọba naa bi o tilẹ jẹ pe yoo yọri si ikú fun wọn. Bẹẹ ni Ijọba naa bẹrẹ si i dagba, a si n yan eniyan pupọ kun ijọ lai ka inunibini lile si.

Ni ikọọkan wọn pa awọn apọsteli ati ọpọlọpọ awọn ọmọ-ẹyin pẹlu awọn ti wọn faramọ́ ẹkọ Jesu, nitori igbagbọ wọn ninu Jesu. Ṣugbọn wọn ni igbẹkẹle ti o nipọn to bẹẹ ninu Ijọba ti O ti waasu ti o fi jẹ pe wọn kò lọra lati kú ki wọn ba le jere awọn ẹlomiran fun Ijọba naa.

### Itara Ailọgbọn

Igba Okunkun de nigba ti ọkẹ aimoye ajẹrikú fi ẹmi wọn lelẹ nitori igbagbọ wọn. Ṣugbọn njẹ Ijọba naa parun? Siwaju ati sokesoke ni irugbin mustardi naa n dagba – o si n dagba sibẹ lonii pẹlu. "A o si wasu ihinrere ijọba yi ni gbogbo aiye lati ṣe ẹri fun gbogbo orilẹ-ède; nigbana li opin yio si de" (Matteu 24:14). Eyi n sọ nipa opin igba yii, ki i ṣe opin Ijọba naa. Ijọba yii yoo maa wà titi laelae. Ni akoko Ijọba Ẹgbẹrun Ọdun yoo gba gbogbo ayé kan, gbogbo eniyan ni yoo si gbadun anfaani rẹ̀, bi ti awọn ẹyẹ ti o wà lara ẹka igi mustardi.

### Iwukara

Jesu tun pa owe miiran fun awọn eniyan eyi ti o ṣapejuwe bi Ijọba Ọrun ti n tàn kaakiri. Eyi ni wiwu iwukara ninu ounjẹ. Bi iwọ ba ti ri ẹni ti n ṣe akara (burẹdi), iwọ a ti ṣe akiyesi pe iba iwukara kiun ti a ba fi kún iyẹfun pipo a maa mu ki o wú. Ideri lori awo kò ni le de e mọlẹ; agbara iwukara pọ to bẹẹ ti iyẹfun pipo naa yoo fi maa wú sii titi yoo fi ṣi ideri soke.

Awọn eniyan buburu lati igba de igba ni wọn ti gbiyanju lati fi "ideri" de Ihinrere. Wọn ti ṣe inunibini gidigidi si awọn Onigbagbọ pẹlu ète ati pa iwaasu Ijọba naa run; ṣugbọn Ijọba naa ti n dagba si i lai fi gbogbo idojukọ pè. Iwukara Ihinrere ti dapọ pẹlu oriṣiriṣi iyẹfun gbogbo – o ti tàn ka gbogbo orilẹ-ede aye. Ọrọ Ọlọrun ni, ko si agbara eniyan tabi ti Satani ti o le pa a run kuro lori ilẹ ayé.

### Ohun ti Jijẹ Ọmọ Ibilẹ Ọrun N Beere

Ki ni eniyan ni lati ṣe lati le wọ inu Ijọba yii? Jesu wi pe, "Ki iṣe gbogbo ẹni ti npè mi li Oluwa, Oluwa, ni yio wọle ijọba ọrun; bikoṣe ẹniti nṣe ifẹ ti Baba mi ti mbẹ li ọrun" (Matteu 7:21). O tun sọ pe; "Bikoṣepe ẹnyin ba pada, ki ẹ si dabi awọn ọmọ kekere, ẹnyin ki yio le wọle ijọba ọrun" (Matteu 18:3).

Nigba ti ọmọdekunrin ijoye ọlọrọ ni tọ Jesu wa lati beere ọna igbala, Jesu fẹran rẹ, Oun si ni ayọ lati fẹ gba a ṣe ọmọ-ibilẹ Ijọba Rẹ̀. Ṣugbọn nitori oun ko fẹ lati fi ọrọ̀ rẹ̀ silẹ, ọmọdekunrin naa pada lọ. Jesu wi fun awọn ọmọ-ẹyin Rẹ̀ pe: "Lõtọ ni mo wi fun nyin pe, o ṣoro gidigidi fun ọlọrọ̀ lati wọ ijọba ọrun. Mo si wi fun nyin ẹ̀wẹ, O rọrun fun ibakasiẹ lati wọ̀ oju abẹrẹ, jù fun ọlọrọ̀ lati wọ̀ ijọba Ọlọrun lọ" (Matteu 19:23, 24).

Nitori bẹẹ, a ri i pe awọn ti wọn n dibọn pe Onigbagbọ ni awọn, ti wọn tilẹ n pe "Oluwa, Oluwa", ki yoo wọle bi wọn ko ba gbọran si ifẹ ti Baba; yoo si ṣoro pupọ fun awọn ọlọrọ̀ ti wọn fẹran ọrọ̀ wọn ju Olugbala lọ lati wọle;

o si daju pe awọn eniyan buburu kò ni le wọle rara: “Nitori ẹnyin mọ̀ eyi daju pe, kò si panṣaga, tabi alaimọ́ enia, tabi olojukòkoro, ti iṣe olubọriṣa, ti yio ni ini kan ni ijọba Kristi ati ti Ọlọrun” (Efesu 5:5).

**“Ki Ijọba Rẹ De”**

Ijọba yii ko i ti dagba tan, sibẹ a ṣi n yan awọn eniyan ṣe ọmọ-ibilẹ Ọrun. Awọn ọmọ Ijọba naa ni awọn ti o ni Ijọba yii ninu ọkàn wọn.

Nigba ti Jesu ba tun pada wa, a o gbé Ijọba naa kalẹ ninu ayé, awọn ti wọn si ti jẹ olootọ si Olugbala yoo ni ipin ninu Ijọba Rẹ̀ ninu ayé fun ẹgbẹrun ọdun. Jesu kọ́ awọn ọmọ-ẹyin Rẹ̀ lati gbadura pe: “Baba wa ti mbẹ li ọrun; Ki a bọ̀wọ fun orukọ rẹ. Ki ijọba Rẹ de; ifẹ tirẹ ni ki a ṣe, bi ti ọrun, bẹ̃ni li aiye” (Matteu 6:9, 10). Nigba ti a ba gbe Ijọba Ọlọrun kalẹ ni ayé, ifẹ ti Rẹ̀ ni awọn eniyan yoo ṣe.

**Awọn Ọmọ Ijọba**

Jesu sọ ti akoko yi nigba ti O jẹ Ase-alẹ Ikẹhin pẹlu awọn ọmọ-ẹhin Rẹ̀: “Emi kì yio mu ninu eso ajara mọ́ titi ijọba Ọlọrun yio fi de” (Luku 22:18).

Wo bi o ti ṣe danindanin to lati làkaka lati le ni àye ninu Ijọba naa! A ni lati ri i pe igbesi aye wa n so eso ti Ẹmi: “Ifẹ, ayọ̀, alafia, ipamọra, iwa pẹlẹ, iṣore, igbagbọ, iwa tutu, ati ikora-ẹni-nijanu” (Galatia 5:22, 23). Bi a ba ti yipada ti a si ti “dabi awọn ọmọ kekere”, ti ifẹ Ọlọrun ba si n gbe inu wa sibẹ, awa ni ọmọ Ijọba naa nisinsinyi, a o si ni ipin ninu Ijọba Kristi ninu aye nigba ti o ba tun pada wa.

## AWỌN IBEERE

1. Awọn wo ni a kọkọ waasu Ihinrere ti Ijọba naa fun?
2. Ki ni ṣe ti awọn Keferi yoo fi ṣiwaju wọn?
3. Bawo ni Ihinrere ṣe tàn kalẹ lẹyin ti Jesu ti lọ si Ọrun?
4. Ki ni awọn ọmọ-ẹyin ni lati ni ki wọn to le ni agbara lati waasu?
5. Ta ni n mu ki Ijọba naa rú soke ki o si dagba lonii?
6. Bawo ni a ṣe n gba agbara lati jeere ọkàn fun Kristi?